# KRISTI, ALAGBARA LORI OHUN GBOGBO

## Kolosse 1:9-29; 2:8-19

## ẸKỌ 410 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ninu rẹ̀ ni gbogbo ẹ̀kún Iwa-Ọlọrun ngbé li ara-iyara" (Kolosse 2:9).**

**I Ifẹ Si Awọn Ara Kolosse**

1 Awọn ará ni ilu Romu n dupẹ fun ipilẹ rere ti Ijọ Kolosse ni, Kolosse 1:3, 4

2 Wọn gbadura fun idagbasoke si i nipa ti ẹmi, Kolosse 1:9-11; Johannu 17:9, 15-23; Efesu 1:16, 17

3 Paulu rán awọn ará Kolosse leti pe igbala ati irapada wà nipa Etutu ti Kristi ṣe, Kolosse 1:13, 14; Romu 3:24, 25; Titu 2:14; Heberu 9:12; Ifihan 5:9

**II Wiwa-Ṣaaju Ohun Gbogbo Kristi Gẹgẹ Bi Ọlọrun**

1 Kristi ni aworan Ọlọrun, Kolosse 1:15; 2:9; Johannu 14:9; Heberu 1:3

2 Kristi ni ẹlẹda ohun gbogbo Oun ni o si mu ohun gbogbo wà, eyi ti a n ri ati eyi ti a kò ri, Kolosse 1:16, 17; Johannu 1:3, 4; Heberu 1:2, 3

3 Kristi ni Ori Ijọ, ati akọbi ninu awọn ti o kú, Kolosse 1:18, 19; 1 Kọrinti 15:20; Efesu 1:22

**III Kristi, Olupilẹṣẹ Irapada Fun Araye**

1 A ṣe eto alaafia ati ibálaja nipa Etutu kan naa, Kolosse 1:20-22; Isaiah 57:21; Romu 5:10, 11

2 Igbesi-ayé mimọ́ ati ailẹgan nipa ti ẹmi wà lori diduro-ṣinṣin ninu igbagbọ́, Kolosse 1:22-25; Johannu 8:31

3 Kristi ninu Onigbagbọ́ ni ohun ìjinlẹ naa, Oun ni O si n sọ ọ di pipe, Kolosse 1:26-29

**IV Pipé ninu Kristi**

1 Onigbagbọ́ pé ninu Kristi; isọdimimọ́ a maa fun ni ni pipé Onigbagbọ́, Kolosse 2:8-11; Johannu17:17; 1 Kọrinti 1:30; Efesu 5:26; 2 Timoteu 2:21; Heberu 10:10; 13:12

2 Nipa ti ẹmi a maa n mú ikú Kristi, isinku ati ajinde Rẹ̀ ṣẹ ninu Onigbagbọ́, Kolosse 2:12, 13; Romu 6:3-5

3 Awọn ọmọ Ọlọrun a maa jẹ adùn didi ominira ninu Kristi, Kolosse 2:14-19; Johannu 8:36; Efesu 4:16

## ALAYE

**Ijọ Kolosse**

Ilu Kolosse jinna to nnkan bi ọgọrun mile si ilu Efesu. Bi o tilẹ ṣe pe Paulu ti rin irin-ajo lọ si ibi pupọ ni agbegbe yii, kò sọ gbangba ni ibikibi ninu iwe rẹ̀ pe oun dé ilu Kolosse. Bi a ba ka Kolosse 2:1, yoo dabi ẹni pe ko i ti de ibẹ nigba kan ri, nitori o kọwe nipa aniyan ọkàn rẹ̀ fun awọn ti kò i ti ri oju rẹ̀ nipa ti ara. Laiṣe ani-ani nipa aṣeyọri iṣẹ-iranṣẹ Paulu ni Efesu, Ihinrere n tankalẹ ni awọn ilu agbegbe yikaakiri, nitori ninu Episteli yii o darukọ awọn ijọ Laodikea ati Hierapoli awọn ilu ti o sunmọ Kolosse.

Filemoni jẹ ọ̀kan ninu awọn aṣaaju ti i ṣe olooótọ ni Kolosse, ati pe o ṣeeṣe ki o jẹ ile rẹ̀ ni ile isin wà (Filemoni 2:7). Ni akoko ti Paulu wà ninu ẹwọn ni a jere Onesimu, ọmọ ilu Kolosse, fun Kristi. Ọmọkunrin yi jẹ isansa iranṣẹ Filemoni, Paulu si rán an pada (si ọdọ ọga rẹ̀) pẹlu iwe ti o mu ni lọkàn ṣinṣin ti a pè ni Episteli si Filemoni. (Ka Kolosse 4:9; Filemoni 10-12).

O jọ pe aṣaaju miiran ni ijọ Kolosse ni Epafra i ṣe, ẹni ti i ṣe olooótọ iranṣẹ Kristi (Kolosse 1:7), ẹni ti o si fi otitọ ọkàn gbé awọn ara Kolosse lé ọkàn rẹ̀ ninu adura gbigbona (Kolosse 4:12, 13). Boya Epafra ni iyipada rẹ̀ ni igba iṣẹ-iranṣẹ Paulu si Efesu. Ọnakọna ti o le jẹ́, ki i ṣe pe Epafra fẹran awọn eniyan rẹ̀ nikan, ṣugbọn o fẹran Paulu o si ba a lọ titi de Romu lati wà pẹlu rẹ̀, lati ṣe iranṣẹ fun un, ati lati ṣe alabapin ninu tubu pẹlu rẹ̀. Nigba ti ọgbẹni yii royin ni rere nipa igbagbọ́, ifẹ ati ireti ti ijọ Kolosse ni, ọkàn Paulu yọ̀ pẹlu idupẹ (Kolosse 1:3-5). Niwọn bi o tilẹ jẹ pe Paulu jẹ

Apọsteli awọn Keferi, o tẹ̀ siwaju lati kọ Episteli yii si ijọ Kolosse bi o tilẹ ṣe pe oun kò ti i ri oju wọn ri.

### Ibẹrẹ ti O Kún Fun Ireti Pupọ

Bawo ni ọkàn Paulu Apọsteli, ondè nì, yoo ti kún fun ayọ̀ pọ̀ to nigba ti o gbọ́ ihin rere lati ijọ Kolosse! Ṣugbọn Paulu, pẹlu iriri ọpọlọpọ ọdun gẹgẹ bi Onigbagbọ́, mọ pe ibẹ̀rẹ rere nikan kò tó. O mọ pe idanwo pupọ, iyiriwo ati ewu yoo wà ninu ijagun ti ẹmi fun ijọ titun yii ni ọjọ iwaju. Ifẹ ọkàn Paulu ati adura rẹ̀ ni pe ki wọn le kun fun imọ ifẹ Ọlọrun ninu ọgbọ́n ati oye gbogbo nipa ti ẹmi; ki wọn ki o le "mã rin ni yiyẹ niti Oluwa si iwu gbogbo, ki ẹ ma so eso ninu iṣẹ rere gbogbo, ki ẹ si mã pọ si i ninu imọ Ọlọrun; ki a fi ipá gbogbo sọ nyin di alagbara, gẹgẹ bi agbara ogo rẹ̀ ninu suru ati ipamọra gbogbo pẹlu ayọ̀."

Ọkàn gbigbooro ti Paulu ni si wọn ni pe ki wọn le maa pọ̀ si i ninu ẹ̀bun ati oore-ọfẹ ti ẹmi. Ifẹ ọkàn rẹ̀ ni pe ki wọn maa tẹ̀ siwaju ninu igbagbọ́, ki wọn jinlẹ ki wọn si fi ẹsẹ mulẹ, ati ni opin ki a le mu wọn de iwaju Kristi ni "mimọ́ ati ailabawọn ati ainibawi."

### Jinlẹ Si I Ninu Imọ Kristi

Awọn ara Kolosse ni imọ otitọ́ gẹgẹ bi o ti wà ninu Jesu, ṣugbọn giga, ìjinlẹ, gigun ati fifẹ̀, wà ninu imọ ti Onigbagbọ́ gbọdọ ni ti a ko si le de opin rẹ̀ lẹ̀ẹkan ṣoṣo. Eniyan ti i ṣe ẹni mimọ́ julọ kò le ṣiwọ ẹ̀kọ́ kikọ́. Gbogbo Onigbagbọ́ gbaa ni o ni lati maa fi imọ kun imọ ki wọn si maa du u gidigidi lati wa-ilẹ-jin, lati ni oye kikún ninu ohun ijinlẹ Ọlọrun ati oore-ọfẹ Rẹ̀.

Ọ̀kan ninu awọn ohun ijinlẹ Ihinrere ti o jinlẹ jù lọ ni pe Jesu le maa gbé inu ọmọ-eniyan ninu ayé yii, sibẹ ki O tun jẹ́ ọ̀kan ninu Iwa Ọlọrun, ati Mẹtalọkan iyanu. Filippi wi fun Jesu pe, "Oluwa, fi Baba na hàn wa, o si to fun wa. Jesu wi fun u pe, Bi akokò ti mo ba nyin gbé ti pẹ to yi, iwọ kò si ti imọ̀ mi sibẹ̀ Filippi? ẹniti o ba ti ri mi, o ti ri baba" (Johannu 14:8, 9). Paulu sọ pe Jesu ni aworan Ọlọrun Ẹni airi. O ni gbogbo ẹwà, agbara, ati ẹda Ọlọrun.

Gbogbo ẹda ti ọwọ́ Jesu wá gẹgẹ bi wọn ti ṣe ti ọwọ́ Ọlọrun wá. Johannu wi pe "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo, lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da." Paulu Apọsteli, nipa imisi Ẹmi Mimọ́, sọ pe ohun gbogbo ti n bẹ ni ayé, bẹẹ naa ni, ni ọrun pẹlu, eyi ti a fi oju ri ati eyi ti a kò ri, ni a dá nipa aṣẹ Ọlọrun. Nihin yii a kò ri ohun kan nipa ẹ̀kọ́ atọwọda eniyan pe n ṣe ni eniyan dagba de ipo ti a wà yii lati ẹda kekere kan ninu omi. Ẹkọ arosọ pe n ṣe ni ayé yii paapaa n dagba diẹdiẹ lati aimoye ọdun gbọọrọ duro lori oriṣiriṣi ahesọ ti kò le so pọ̀. Ẹkọ arosọ yii ko tilẹ fi igbakan ni ẹsẹ nilẹ nitori o ṣe dandan pe ki wọn maa ṣe ayipada rẹ̀ lati igba-de-igba nitori awari titun ti o n gori ara wọn ninu imọ ijinlẹ, ṣugbọn lati irandiran Ọrọ Ọlọrun duro gbọnin-gbọnin kò si ti i yipada. Ọpọlọpọ awari imọ ijinlẹ ko ti i mu ki o ṣe dandan lati yí Ọrọ Ọlọrun pada. Dajudaju, dipo eyiini, awọn awari wọnyii tubọ n fi idi Bibeli mulẹ ni, wọn si n jẹri si otitọ nì pe "awọn enia mimọ Ọlọrun nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ́ wá" (2 Peteru 1:21).

Ẹlẹda nla nì, gẹgẹ bi Paulu ti wi, ni Ori ara - Ijọ. A kò fi ipo yii fun angẹli kan, ki i si ṣe fun eniyan ẹlẹran-ara-kan - awọn ẹda ọwọ Rẹ̀ - ṣugbọn fun Ẹlẹda nikanṣoṣo ni, ki i si ṣe nitori ti O jẹ Ẹlẹda nikan, ṣugbọn nitori ti I ṣe Olurapada pẹlu. Oun, Ẹniti i ṣe Ẹlẹda, "si mu awọ̀ iranṣẹ, a si ṣe e ni awòran enia. Nigbati a si ti ri i ni iri enia, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, o si tẹriba titi di oju ikú, ani ikú ori agbelebu" (Filippi 2:6-8). Gbogbo eyi ṣẹ, ki O ba le ra awọn ọkàn ti o ṣegbe pada, ki O si le dari ẹ̀ṣẹ ji gbogbo ọmọ eniyan ti wọn ti ṣubu, O ṣe eto alaafia nipa bibá ohun gbogbo laja sọdọ ara Rẹ̀! Igbala nla yii jẹ́ ohun ijinlẹ ti o tobi pupọ, Paulu sọ fun awọn ara Kolosse pe ohun ijinlẹ naa ni "Kristi ninu nyin, ireti ogo."

### Isọdimimọ́

Paulu kọ iwe si awọn ara Kolosse wi pe, "A ti fi ikọla ti a kò fi ọwọ kọ kọ nyin ni ila, ni bibọ ara ẹ̀ṣẹ silẹ, ninu ikọla Kristi." Bawo ni Paulu yoo ti kún fun ọpẹ to nipa mimọ̀ pe a ti fi ẹ̀kọ́ isọdimimọ́ kọ́ awọn ara Kolosse, pe ikọla ti inu ọkàn wà nipa eyi ti gbòngbo ati ẹ̀dá ẹ̀ṣẹ maa n tu kuro. Ki i ṣe pe Paulu tun n fẹ mu wọn pada sabẹ akoso Ofin nigba ti o sọ̀rọ nipa ikọla (ti i ṣe eto labẹ Ofin, ti o si tọka si isọdimimọ́), ṣugbọn oun n sọ nipa ikọla ti inu ọkàn lati ọwọ́ Kristi. Kristi ti wá, O si ti mu gbogbo ilana Ofin, itọkasi rẹ̀ ati ojiji rẹ̀ de opin.

Jesu ti kú fun ẹ̀ṣẹ wọn, a si ti sin In, O si ti jinde fun idalare wọn; lati ṣe ẹri fun eyi a ti ṣe iribọmi fun wọn. (Ka Romu 6:3, 4). A kilọ fun awọn ara Kolosse lati má fi ara wọn si inu idè tabi

ki wọn fi aafo silẹ fun ẹnikẹni lati maa ṣe idajọ wọn nipa jijẹ tabi mimu, tabi pipa ọjọ mimọ́ tabi ọjọ isinmi mọ́ tabi nipa apejẹ oṣu titun. Nitootọ, pupọ ninu awọn ilana wọnyii ni Ọlọrun tikara Rẹ̀ gbekalẹ, ṣugbọn a fi wọn fun ni fun saa kan ni, akoko ti a n pè ni igba Ofin; Ofin naa si jẹ olukọni lati mú wọn wá si ọdọ Kristi. Nitori naa ni Paulu ṣe sọ pe ojiji ohun ti o n bọ̀ wá ni Ofin i ṣe, ṣugbọn ara (ti o ni ojiji) ni Kristi ẹni ti O mu gbogbo Ofin ṣẹ.

A kilọ fun awọn ará Kolosse nipa ewu awọn ẹlẹsin Ju ti o n fẹ mu wọn wá sabẹ ide Ofin. Paulu tun kilọ fun wọn pẹlu nipa awọn wọnni ti wọn n fẹ fi "imọ ati ẹ̀tan asan" mu wọn pada sinu awọn nnkan ayé. Ṣugbọn lẹyin ti a ti sọ wọn di ẹbi Ọlọrun, alajọpin pẹlu Kristi, Ẹni ti i ṣe Ẹlẹda ati Olurapada nla nì, wọn ti di pataki Ẹya Ara Kristi ni isopọ ṣinṣin ninu iṣọkan igbagbọ́ ati idipọ alaafia. Kò si agbara kan ninu ayé tabi ni ọrun apaadi ti o le já okùn irẹpọ bi iru eyi; ṣugbọn alagba Apọsteli yii mọ̀ pe o kù si ọwọ olukuluku bi yoo bá duro ninu igbagbọ́. Bi olukuluku wọn ti ni ominira lati dáyàn, wọn le já ara wọn gbà kuro lọwọ Oluwa ki wọn si ti ipa bẹẹ sọ gbogbo anfaani Ihinrere Jesu Kristi nù. Ṣugbọn bi wọn ba fi otitọ ọkàn pa igbagbọ́ wọn mọ́, ki wọn si di igboya wọn mu ṣinṣin titi de opin, wọn yoo maa dagba si i ninu oore-ọfẹ Ọlọrun bi wọn ba ti n ni imọ Ọlọrun siwaju si i, ni opin rẹ̀ wọn yoo si jẹ́ ajogun pẹlu awọn eniyan mimọ́ ninu imọlẹ, bẹẹni wọn yoo ni ayọ̀ Ọrun titi ayeraye.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni o mu ki Paulu kọ iwe si awọn ara Kolosse nigba ti o ṣe pe ko i ti i fi oju kan wọn ri?

2 Paulu fi Kristi wé Ọlọrun; ṣe apejuwe ifiwera naa.

3 Ẹsẹ kin-in-ni ninu Bibeli kà pe, "Li atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiye." Bawo ni a si ṣe le pe Jesu ni Ẹlẹda ohun gbogbo?

4 Ki ni ṣe ti a fi pe Kristi ni Ori Ijọ?

5 Ṣe alaye bi a ti mọ pe awọn ará Kolosse ti ni ẹ̀kọ́ isọdimimọ́ ati iribọmi.

6 Ki ni ohun ijinlẹ ti Paulu sọrọ rẹ̀?

7 Opin wo ni Paulu n fẹ ki awọn ara Kolosse ati olukuluku eniyan dé?